# ENMO PAGIDARI! ELEDE JE OMO ENIA




STANDARD NEW KING
SIZE 4D SIZE 5D.
See you pay the correct price.



ELETI OFE
A-NJU-WON KO SE WI L'EJO



U. T. C.
SERVES
YOU
WELL



VOL. No. VIII 483. ELETI - ỌFẸ LAGOS, SATURDAY, SEPTEMBER, 1, 1956. KỌBỌ MEJI (2d.)


## Enmo Pagidari! Elede Je Omo Enia

ILẸ AWORI. Ọkunrin kan wa ti a npe ni Jọ-ọda (Ọjọ-yi-o-da) o jẹ gbajumọ kan ti oju gbogbo enia mọ nilẹ Awori. O ni owo, o kọle, o ni ọpẹlọpọ adiẹ o si ni awọn ẹlẹdẹ pupọ ju ẹnikẹni lọ nilu rẹ. Ko sibiti awọn ẹlẹdẹ nwọnyi ko le wọ ninu ile ọkunrin na, bi nwọn ba wọ yara ko jẹ titori rẹ ba wọn wijọ.

Ṣugbọn bi o ti lowo, ti o si gbajumọ to yi ko bimọ. Obinrin mẹfa lo ni, o wa lọ yẹwo lọdọ Babalawo wipe njẹ on yio bimọ laiye yi? Nwọn wi fun pe, ọmọ kanṣoṣo lo ku fun lati bi; bi ko ba ko awọn ẹlẹdẹ rẹ kuro, ko le bimọ. Ọkunrin yi kọ lati ya pẹlu awọn ẹlẹdẹ rẹ.

Laifa ọrọ gun iyawo igbẹhin bimọ ọkunrin kan fun Jọọda inu rẹ dun, o ṣe ikomọ na, aiye gbọ, ọrun mọ; o daṣọ, gbogbo nkan lo ṣe lati fi tẹ ọmọ rẹ lọrun. Egberegbe, egberegbe, iya ọmọ na tẹ ọmọ rẹ silẹ, o npọn ẹkọ ti yio gbe lọ ta ni ọja, apẹrẹ ẹkọ tikun, ọmọ na si sun, o wa dide lati lọ mu apẹrẹ miran ninu ile

Ki o to de ẹlẹdẹ ti gbe ọmọ lọ nibiti osun si, nwọn ti jẹ agbẹdu rẹ dalu, nigbati o pada de ko ri ọmọ lo ba fi ibosi ta. Ẹnikan taju kan, lo ri awọn ẹlẹdẹ ti o njẹ oku ọmọ na.

Nigbati Jọọda de, ti nwọn rohin iṣẹ ti awọn ẹlẹdẹ rẹ ṣe, o bu si ẹkun nigbati nwọn ṣe arọwa fun, o gbọ, o dakẹ, nigbati o dide o fa ada yọ, o si pa gbogbo awọn ẹlẹdẹ rẹ run. O pin gbogbo dukia rẹ fun awọn iyawo rẹ tan o gbe iya ọlọ kan sinu ọkọ, o wọkọ, o si lọ s'oju omi. Alọ ni a ri, a ko ri abọ rẹ doni. Ori ọkẹrẹ ko ko l'awo, bi a wi f'ọmọ ẹni a gbọ.


THE NATIONAL BANK
Of Nigeria Limited.

Ile ifi Owo pamọsi yi
Nfi ọna owo han ẹni
Bi o ba fẹ jẹ oniṣowo pataki ao
ran ọ lọwọ nipa wipe ao tọ ọ
si Ọna ti o dara, ao la oju rẹ
si Ọna owo lati ilu Okere wa
Bakanna a si ni a tun nṣe iranlọwọ fun
gbogbo oja ilẹ wa ti anta si agbaiye.

ILE IṢẸ WA NI EKO :—
37, Marina Street, P. O. Box 508, Lagos.

AWỌN AṢOJU WA NILU ỌBA NIYI :—
The National Provincial Bank (Overseas Branch)
1, Princess Street, London E. C. 2.

The Comptoir National Descompte, De Paris.
8/13, King Williams Street, London E. C. 4.


## Iwadi Oro Bank Azikiwe

Eniti a nwoyi ni Ọgbẹni Dọkita Nnamidi Azikiwe, eniti ijọba Gẹsi titori rẹ yan awọn ọjọgbọn ninu ofin wa silu Eko lati wa ṣe iwadi nipa Ọgbẹni na ati Continental Bank Ltd.



Dr. NNAMDI AZIKIWE

Bi ọrọ na ti lọ niyi Ọgbẹni E, O, Eyo ti o nṣe sorekode fun ijọba Ila-orun ninu igbimọ lo fi ẹjọ Dọkita Azikiwe sun wipe, mọnọfiki wa larin rẹ ati Baaki ti o da silẹ. O gbe ọrọ yi si gbimọ ṣugbọn awọn igbimọ taku lati gbọ ọ.

Ọrọ yi lo d'orun ohun ti Ṣẹkitẹri agba nilu Oyinbo da si, Eyi lo mu Azikiwe binu sọ wipe, on ko fẹ ki ẹnikan ma kọ on ni nkan ti on ni lati ṣe, Ẹnikini faa ta, ẹnikeji faa ta, ni ọrọ na ba di ohun iwadi.

Lọya mẹta ni Dokita Azikiwe gba lati ilu ọba wa enia dudu kan lo ṣikẹrin, Ọgbẹni Eyo gba lọya oyinbo meji o si gba enia dudu meji.

Ṣẹkitọri agba gba lọya meji, Continental Bank gba lọya enia dudu mẹrin. Awọn Minister ti ijọba Ila-orun gba lọya mẹfa, Professor Eyo Ita, ati Principal Ikoku gba Lọya meji oyinbo kan, B, B, W, A. Ltd. gba lọya oyinbo meji.

Iwadi ọrọ na yio bẹrẹ ni Monday ti o mbọ.

## ỌRỌ ṢỌṢI NIWAJU ADAJỌ

ILESHA. Ọrọ ko dun nigbati awọn ijọ Ọlọrun meji dide si ara wọn, ẹmi Ọlọrun fo lọ kuro ninu wọn, awọn si di ijọba eṣu eṣu mu, ọmọ ina l'a nran si ina. Ọrọ na ko ṣe yanju ayafi igbati awọn Ọlọpa de ibẹ. Agbare-gbabọ, ọrọ na ni lati lọ siwaju atẹ idajọ.

Bi a ti gbọ, ti ọrọ na lọ niyi:- Okan ninu awọn alufa ijọ yi ti o ti fi ijọ wọn silẹ, ti o si ti lọ dapọ mọ awọn ijọ miran, ni a gbọ wipe, o tun pada sinu ijọ rẹ ti o ti fi silẹ nigbati nkan ko rọgbọ fun lọhun.

Dide ti ọkunrin na pada de nwọn ni o ṣiwaju ṣe isin fun awọn ijọ eyi ni ohun ti awọn ijọ na lodi si, ti nwọn si taku pe, ko gbọdọ ṣe isin fun wọn nitoripe iru ẹkọ ti nwọn nkọ wọn ninu ijọ ti o ti nṣe ri, ni yio wa fi kọ wọn.

Alufa na sọ wipe o di ogun ọdun ti on ti nṣiwaju ṣe isin fun awọn ijọ na bawo ni on yio ti ṣe wasu eke fun awọn ijọ. Awọn ijọ na kọfẹ.




AWOGBA
Oogun fun
Girl,
Ka Tir Ni
Ile
— ISE —
Olodumare
Okebola,
115, Great
Bridge St.
LAGOS

# Owo koko ipinle Iwo orun yio din ni odun to mbo

Eyi li alaye ti a ṣe lori owo Koko ninu ipade kan ti a ṣe pẹlu awọn oniwe irohin ati Adele Alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ-orun. Ọlọla Oloye F. R. A. Williams, Ọlọla Oloye C. D Akran, Alaga Igbimọ ti nmojuto tita Koko ati awọn ẹmẹwa rẹ, ni Ibadan lowurọ ojọ keji oṣu yi.

Igbimọ ti nmojuto tita Koko ni Ipinlẹ Iwọ-orun ṣe ipade kan laipẹ yi, o si pinnu pe owo Koko fun ọdun ti mbọ yio jẹ adọjọ poun fun Koko to ba wa ni ipo kinni ati pọnun marundinlogoje fun Koko to ba wa ni ipo keji.

Ijọba Ipinlẹ Iwọ-orun ti fi aṣẹ si ipinnu na, Igbimọ ti nṣeju awọn olowo Koko ni Ipinlẹ yi si ti fọwọsi i.

Igbimọ to ṣe ipinnu na sọ ohun to fa ẹdinwo na ati ero gbogbo ti nwọn fi lu ọran na ki nwọn to ṣe ipinnu.

Lọdun to kọja, Igbimọ ti nmojuto tita Koko pinnu pe ki owo tọnun kan jẹ igba pọnun nigbati ọja Koko ni agbaiye ti fọ, ti a si mọ pe ninu owo ti a ti fi pamọ li a le ma mu fi san owo na titi di ọdunni. Larin na, ọja Koko ni agbaiye tubọ fa sẹhin, o si di ohun ti Igbimọ na ni lati fi igba ọkẹ pọnun kun iye ti a nta koko ki a to le san igba pọnun na.

Ohun ti o mu ki ọja Koko ni agbaiye fọ ni pe Koko pọ ni ilu gbogbo ti ngbin Koko ati pe awọn to nra Koko si ni ọpọlọpọ Koko lọwọ. Diẹdiẹ ni nwọn nlo eyi ti o wa li ọwọ wọn, nwọn ko si ni ọna ti nwọn le gba, ti owo Koko le fi lọ soke. Bi o ti lẹ jẹ pe a ko ṣairoye pe ojọ ọla yio dara, sibẹ-sibẹ, ko daju pe owo Koko le tete lọ soke.

Ohun ti a ri nipe Koko yio dara ni Ipinlẹ Iwọ-orun lọdun to mbọ. Awọn ọja ti a nra lati ilu okere yio si wa ni ipo to tẹrun. Eyi yio si ṣe dede pẹlu owo awọn agbẹ, ki yio si jẹ ki ẹdinwo to wa fun Koko nisisiyi pa wọn lara.

Iṣẹ ti Igbimọ ti nmojuto tita Koko nipe ki o ṣatilẹhin fun awọn agbẹ nigbati owo Koko ba lọ silẹ. Lori eyi Igbimọ na gbodọ wo iwaju, ki o si ṣeto owo ti a le ma san fun Koko lọdọdun,

Nisisiyi, Igbimọ na ti mu adọta pọnun kuro ninu owo Koko, ṣugbọn o yẹ ki a ṣakiyesi pe owo Koko ni agbaiye din nkan bi adorin Pọun lọdun to kọja nigbati Igbimọ na san Igba poun fun awọn agbẹ. Adọjọ ponun ti a kede lọdunni li owo to kere ju ti Igbimọ na ṣeleri lati san fun awọn agbẹ lọdun to kọja. Igbimọ na yio tun mu owo bi adọta ọkẹ pọnun ninu iṣura rẹ lati san owo yi fun awọn agbẹ nitoripe ko si idaniloju pe ọja Koko yio gberi bi a ti ro ki a to ṣe ipinnu adọjọ pọnun na. Bi nkan ba si buru ju bi a ti ro, Igbimọ na le faradi owo bi ọgọrun ọkẹ ati ẹdẹgbata pọnun ki o to le san adọjọ pọnun na fun awọn agbẹ.

Ni ilẹ Aganyin, owo Koko kere pupọ si ti ilẹ wa nihin. Iwọnyi li eto owo Koko ni ilẹ Aganyin ati ilẹ wa fun ọdun marun to kọja:

Ni idunrun si idunrin —

Ni ilẹ Aganyin; ẹru kan jẹ pọnun mẹta abọ; tọnun kan jẹ adọje pọnun, ṣilẹ metala, ati kọbọ mẹrin—(£130 13s 4d)

Ni ilẹ wa: tọnun kan jẹ adọsan pọnun [£170].

Ni idunrin si idunta —

Ni ilẹ Aganyin; ẹru kan jẹ pọnun mẹta ati ṣile mejila, tọnun kan si jẹ pọnun mẹrinleladoje ati ṣile mẹjọ (£134 8s)

Ni ilẹ wa: tonun kan jẹ adọsan pọnun (£170).

Ni idunta si eṣi—

Ni ilẹ Aganyin; ẹru kan jẹ pọnun mẹta ati ṣile mejila tọnun kan si jẹ pọnun mẹrinleladoje ati ṣile mẹjọ (£134 8s).

Ni ilẹ wa: tọnun kan jẹ igba pọnun (£200)

Ni eṣi si ọdun yi—

Ni ilẹ Aganyin: ẹru kan jẹ pọnun mẹrin, tọnun kan si jẹ pọnun mọkandinladọjọ ṣile mẹfa ati kọbọ mẹjọ (£149 6s 8d)

Ni ilẹ wa: tọnun kan jẹ igba pọnun (£200),

Fun ti ọdun to mbọ, Igbimọ ti nmojuto tita Koko ni ilẹ Aganyin ti pinnu lati san pọnun mọkandinladọjọ, ṣile mefa ati kọbọ mẹjọ (£149 6s 8d,) fun tọnun kan.

Bakanna, Igbimọ ti nmojuto tita Koko ni ilẹ Kamẹrun ti pinnu lati san adọjọ pọnun (£150 fun tọnun kan lọdun to mbọ.

---

# Ikomo to Larinrin

Ọgbẹni D. O. Ladipọ ti ile iṣẹ P. W. D. ni Ijọra ṣe ikomọ ọmọ rẹ Ọkunrin ni ile rẹ No. 7, Berkley St. Ebute Mẹtta ni ọjọ Satide tokọja.

Nwọn sọ ọmọ na ni oruko Abayọmi Ọlaniyi. Awọn ọrẹ, ẹbi ati ojulumọ l'o pesẹ sibi ikomọ na. Iyafin D. O. Ladipọ ṣe gudugudu meje l'ọjọ na, bẹni Tunde Onilu fi ilu rẹ dabira ati orin to gbadun.

Diẹ ninu awọn enia pataki ni. Ọgbẹni J. O. Hyde ati iyawo rẹ, S O. Labode ati iyawo, D. B. Williams ati iyawo, S. B. Adeniregun ati iyawo rẹ, S. O. Ṣogbọla ati iyawo rẹ, nwọn Ogbẹni Pan Lawal Oriade Wellington, O. A. Akinjọbi S. Adebakin ati E. O. Akinshile,

Baba ọmọ fi jijẹ ati mimu tẹ gbogbo enia lọrun.

---

# Elewon kan lu Ajele

GBOKO Ọkunrin kan ti a npe ni Sabo Abudulabi nilu Gboko lo daran ofin ti nwọn si fi si ẹwọn oṣu mejidilogun.

Ajẹlẹ dide lọ si ọgba ẹwọn nipa ọrọ ti Sabo Abudulabi yi, nitoripe, o sọpe ẹjọ ti nwọn ju on si ẹwọn fun yi ko tẹ on lọrun.

Ṣugbọn nigbati Sabo fi oju kan Ajẹlẹ yi, ninu ọgba ẹwọn, o sare mọ, o kan lẹṣẹ. Lori ẹṣẹ ti o kan Ajẹlẹ yi ni nwọn tun ba ṣe ẹjọ Adajọ ni ki nwọn lọ na a ni ẹgba mejila nidi rẹ, bẹni oju rẹ da wayi.

---


# CARSON'S PAINTS AND VARNISHES




SOLE AGENT:-
IKORODU TRADING COMPANY
20 & 28 BALOGUN STREET, LAGOS.


---

# Nigerian Railway Corporation

## Closing Of Apapa Road

This is to warn the general public that main road from Ebute Metta to Apapa will be closed to all traffic from 9 p.m. on Saturday, 8th September, 1956, to 8th September, 1956, in order to effect certain repairs to a level crossing.

**R. B. Emerson**
**General Manager.**

Nigerian Railway Headquaters,
EBUTE METTA.
27-8-56.

## Irora Orikerike

Boya Kidinrin le fa a

Ise Kidinrin ni lati mu awon idoti ti o mbe ninu eje ara kuro nigbati ko ba sise dara-dara idoti na awojo po sibikan, eyi lo njeki awon orike bere si dun ni.

Ohun ti a le fi wosan ni wipe ka se iranlowo fun Kidinrin na ki o le sise rere. Egbogi De Witts na kak'ri aiye ni a si nta egbogi n a a Ọpọ niau iwe ni a ti ri gba lati ọdọ orisirisi enia ti awọn nsọ iru iṣẹ ti De Witts ṣe fun awọn Danwo lọra ọkan ni ṣọbu egbogi



Ohun ti o nfa nigbati Kidinrin ko ba sise tara, sugbon bi enia ba ti lo egbogi yi alafia yio desi oluwa re, nitoripe ara Kidinrin ni yio ti sise. Danwo lo ra ni sobu egbogi.

**DE WITT'S PILLS**
for Kidney and Bladder Troubles

## Gba'jare o Tani L'omo Yi o

OBALENDE. Awọn olotu ijọba tun ri ọmọ jojolo kan ẹjẹ ọrun he nibiti nwọn gbe tẹ sinu apoti ọti Bia lẹgbẹ ilewe St. Greogry College ni Ọbalende, Gbaja-re-o-o, tani l'ọmọ ikoko yi?

Bayi na ni obinrin Hausa kan bimọ tan ni Ita Alagba nijọsi, ti o wa lọ tẹ ọmọ na si adugbo kẹdọgbọn. Opẹlọpẹ Ọgbẹni Idewu lo jẹ ki nwọn ri ọmọ na gbejo loni. Nigbati awọn Ọtẹlẹ - muyẹ tẹsẹ bọ ọ, nwọn wa Iya na kan t'o bi ọmọ nita Akanni.

Awọn alaṣẹ ti gba lati ma ṣe tọju ọmọ ti nwọn ribe ni Ọbalende yi titi nwọn o fi ri Iya rẹ, a si gbọ wipe awọn alaṣẹ ti nwadi ile ti a ti bi ọmọ na.

## E Maka Iwe Irohin Eleti-Ofe Ki E si ma Polowo Oja Yin Sinu Iwe Irohin Aladun Yi



# OVALTINE ni Elere idaraya nmu

Nitoripe Ovaltine nfun ni ni agbara ti oduro O si tun nfun ni ni iṣẹgun. Ere idaraya a ma gba gbogbo okun inu enia lopọlọpọ - Ovaltine a si ma fun ni ni ajẹbo ara titun werewere ati agbara pẹlu okun.

Ọgbọn ẹrọ ni a fi ṣe e lati inu awọn eyin, eso irugbin, wara, ti a si fi nkan elo imarale pẹlu rẹ, Ovaltine gbadun ni mimu o si jẹ onjẹ to baramu pupọ, gbogbo awọn elere idaraya lo nmu nibikibi. Fi Ovaltine ṣe ohun ipanu lọsan ati lalẹ ki o to lọ sun.

*Ovaltine jẹ onjẹ to pe ti o si dara ti o ti nfun enia ni alafia ati pe lati ọdun 1932 ni wọn ti mọ ni pataki nibi ere Olimpik. Awọn elere idaraya ti Olimpik a ma mu Ovaltine nigbagbogbo tori okan ninu ẹkọ iṣẹ wọn.*




# OVALTINE
wa fun agbara at okun

# ELETI QFE

A-NJU-WỌN KO SE WI L'EJQ

EDITORIAL OFFICE & WORKS — 28, Kosoko Street, Lagos, P. O. Box 467

CABLES & TELEGRAMS — "ELETI - QFE LAGOS" Phone 23370

VOL. VIII. NO. 483. LAGOS, SATURDAY SEPT, 1. 1956.


## Iwadi Oro Bank Azikiwe

Gẹ̀ẹ̀bi gbogbo ẹnyin ọkawe wa ti ngbọ nipa irọkẹkẹ iwadi lori oran Owo girimọyan ti awọn Ijọba Ila-Orun (Eastern Government) ko sinu ile Ifowopamọ ti a npe ni African Continental Bank ti Dokita Azikiwe jẹ Oluṭu ile Ifowopamọsi na.

Ọro yi dide lori imọran ti ọkan ninu awọn Ọlọla Olugbimọ Ila-Orun da ninu ajọ igbimọ wọn wipe ki a ṣe ayẹwo ọna ti awọn kowo ijọba Ila-Orun da sinu Bank na nitoripe ko tọ suna l'oju ti on. Eyi l'odogun to d'ọdẹ ti Gomina Ila-Orun fi dasi ọrọ na wipe ki a fi ẹsọ ṣe, ko ma ba d'ariwo.

Agbare-gbabọ, ọga Onikoyi Oko (Secretary of State) nilati fi aṣẹ si wipe ki nwọn ṣe iwadi ododo ati otitọ nipa ọrọ na, ki afi ọwọ wẹ ọwọ ki ọwọ le mọ.

Awọn ogun-a gbomgbo ti yio ṣe iwadi na ti de, wọn si ti berẹ iṣẹ na ni ọjọ Monday ọsẹ yi, ṣugbọn riro ati gbigbọ ọrọ na di ọjọ Monday ọtunla l'agbara Edumare!

Bi ọrọ na ba ti nlọ si ni ao ma ṣe i r o h i n rẹ fun yin ninu Iwe - Irohin wa Eleti - Ọfẹ yi, nitorina ki olukuluku ẹnyin ọkawe wa maṣe jafara lati ma ka Iwe Irohin Eleti–Ọfẹ lọsọsẹ.

## Aj'omogbe Tunde!

Irohin ti a ri gbọ ni wipe ọkunrin kan ni on njẹ Kojere Hausa, ti ko si i'ugbe, ni o tun lọ ji ọ m ọ ekee kan gbe ni Ebute-Mẹtta ni ọjọ Tuesday ọsẹ yi.

A gbọ pe iya ọmọ na fi ọmọ rẹ sọ ọja ti o nta nitosi ile wọn, o lọ ra nkan, kio to pada de Kojere ti mu ọmọ na rin jinna, nibiti ọwọ ti tẹ. O mbẹ lọwọ awọn Ọlọpa nisisiyi.

## Omo n'iyi omo nide.

KANO. Nigbati a w ọ n olorişa ba bimọ nilu Ibadan, ni iwọ yio ma gbọ iru orin bayi pe,

Ọmọ n'iyi, ọmọ nidẹ.
Ko se ma ni o jare,
Omo n'iyi, ọmọ n'idẹ
Ẹ bani gb'ọmọ Oke
Lanti lanti.

Ayọ na ko lẹgbẹ nigbati Ọgbẹni S. B. Ọnabanjọ ti ile iṣẹ C. F. A. O. nilu Kano fi nko ọmọ rẹ obinrin jade, ninu ile rẹ ni Niger Street nigboro ilu Kano.

Alhadji Abdul Aziz lo ke wutuba le ọmọ na lori, o si pe ọmọ na ni orukọ yi Risikatu Abiọla Ọnabanjọ.

Ọgbẹni Ọnabanjọ fi ile pọn ọti, o si fi ọna roka, Ovaltine, Coffiee, Iresi ati Burẹdi jẹ a m u gbadun, Nigbati o di ọjọrọ ti olukuluku enia ti dari wa sile lati ibi iṣẹ, apoti bia meji ni awọn gbajumọ fi panu.

Diẹ ninu awọn ijimi enia ati awọn gbajumọ ti o wa s i b i ikomọ na ni Alhadji Lasaki, A. K. Aderohunmu, Ogali, A. S, Okikiọla, A. O. O s e n i, M. A, Dabiri, Tairu Ọnasanya, Y. A. Dosunmu, Z. M. Ariyọ A. O. B a l o g u n, Sholankẹ, Dawodu; G. A. Shoaga, M. A. Giwa, ati R. L. A. Ajala.

Awọn enia to wa sibi ikomọ na fẹrẹ, to irinwo, baba Ikoko nnawo bi ṣẹkẹrẹ, Ọlọrun ko jẹki ire ọmọ na kari wa o.

## Tani Le Se Kio Gba Ebun

(Lati Ọwọ Ọmọ Adimula)

Ẹnikẹni t i o b a dahun gbogbo ibere isalẹ yi, yio gba ẹbun:-

Ẹbun Kini — 10/-
„ Keji — 5/-
„ Kẹta — 3/-
„ Kẹrin — 2/-

Awọn ibere na niwọnyi:-

1. Ọdun wo ni ijọba da iṣẹ Municipal t a b i Lagos Town Council silẹ ni Eko ?.
2. Kini orukọ Oloye Olumẹgbọn t i o m b ẹ nigbati Ọba Idewu Ojulari nṣe ọba Eko ?.
3. Tani Oloye Ọjọra to mbẹ lori oye, nigbati Gomina Goloba wa ni Eko ?.
4. Nigbati Faro njoye Ọjọra, Ọba wo lo mbẹ ninu Iga Idunganran ?
5. Ọdun wo ni a fi i p i l ẹ ile isin Ararọmi Baptist Church lelẹ ?
6. Kini idi rẹ ti nwọn fi npe Kosọko ni Kosọkọ ?
7. Ọjọ wo, Oṣu wo, ati ọdun wo ni Eṣugbayi E l e k o pada bọwa sile lati Ọyọ ?
8. Kini orukọ obinrin ti o kọkọ ṣiṣẹ adajọ nilẹ Yoruba ati nibo ni ibujoko idajọ rẹ?
9. Tani adajọ ti o da ẹjọ Apalara, ọjọ wo ni nwọn yẹgi fun a w ọ n t o p a alufa na ?
10. Ọba ilu wo ni awọn Ọba ilẹ Yoruba ko gbọdọ foju kan nigbani, ati kini idirẹ ti nwọn ko fi le ṣe bẹ.
11. Mọṣalaṣi wo ni a kọkọ tunṣe daradara ni ilu Eko ?
12. Tani ẹniti nwọn kọkọ npe ni Ọgbẹni Olowo, Ọba wo lo si mbẹ lori oye nigbana.
13. Ọdun wo ni Oloye Amọdu Tijani Oluwa pada bọ lati ilu Ọba, ọmọ ọdun melo

(wo yoku loju ewe karun)


## ABOKI



JẸ AWOGBARUN to LOKIKI KA ILẸ ENIA DUDU.
AJẸBIDAN ni fun IKỌ, LAKUREGBE, IWORA, AKOKORO, S O B I A, AKANDUN, JẸDIJẸDI, etc.

KOṢEFẸKU ni GBOGBONṢE yi jẹ f u n GBOGBO I L E nitorina RA IGO kan LONI Lọdọ:-

IBUKUN - OLU MEDICINE STORES,

Amunigun Street, Box 245, Phone 189x, IBADAN

E 21, Sabongeri, ZARIA, X 5, Central Market, Box 2205,

Kumasi, Gold Coast.

## Eti re melo, kini ofi nse?

ỌRỌ NI MO FI NGBỌ.

Nje o ti gbo pe LISABI ti si Sobu ELUBO won si Eko.

TETE LỌ RA TIRẸ NI

**103, Broad Street, Lagos.**

## Plushes, Velvets, Velveteen, Damasks & Building Materials

PLEASE CONSULT :

## Okunowo Brothers

63 Massey Street, (Faji Market)
LAGOS, NIGERIA.
The house where Courtesy & Satisfation are Guaranteed.

## Egypt ko ni gba enikan laye lori ohun ini won

LONDON. Nipa ede koyede ti o ti mbẹ larin Gẹsi ati Egypt lori itọ odo Suez, ti awọn Egypt ti mba Gẹsi sọ wipe, niwọn igbati Gẹsi ti fun wọn ni ominira, nwọn ni lati fun wọn laye ki nwọn raye ṣelu wọn.

Nitotọ awọn Gẹsi ko ijọba wọn kuro, ṣugbọn nwọn lọ fidi ti si ilu Somaila ni Ebute Suez. Awọn ara Egypt sọ wipe wiwa ni ebute yi ti Gẹsi wa, ko tẹ wọn lọrun ayafi ki nwọn fi aṣẹ ebute na le wọn lọwọ, eyi ni Gẹsi kọ lati ṣe, ni ọrọ na badi gbọnmisi, omikoto. Awọn ara ilẹ Egypt ni lati fi agbara lọ gba ebute na kuro lọwọ Gẹsi.

Eyi ko dun mọ Gẹsi rara. Nigbana ni a ngbọ irọkẹkẹ ogun lati ọwọ Gẹsi si Egypt Awọn ẹgbẹ Majẹobajẹ ti gbogbo agbaiye tẹsẹ bọ ọrọ na, nwọn ni ki Egypt ran aṣoju wa silu Gẹsi ki nwọn le pari ọrọ na.

Nigdati awọn igbimọ na de London, aṣoju Egypt ti o lọ si igbimọ na sọ wipe, Ebute Suez ohun ini babanla awọn ara Egypt ni a ko si ni gba ẹnikan laiye lati joko lori ogun awọn baba wa.

Bi ebute Suez ba wa ni ikawọ awa ara ilẹ Egypt, ao ma fi aye fun ọkọ ilukilu ti o ba fẹ gba ibẹ koja. Ọkọ ti a ko ba jẹki o kọja ki igbimọ Majẹobajẹ ka wa si arufin.

Nipa ileri yi, gbogbo fukẹ-fukẹ ti awọn orilẹ ede ni si Egypt nipa ebute na mu ki irẹwẹsi ba gbogbo enia lori ohun ti nwọn lero lati ṣe. Nihin ni nwọn si ba ọrọ na de.

## Oro Ebute Suez Koiti Loju

LONDON. Ninu igbimọ ti awọn ẹgbẹ Majẹobajẹ lọ ṣe nilu London, nipa edekoyede ti o bẹ silẹ larin Gẹsi ati Egypt nipa ọrọ ebute Zuez, awọn ilu mejilelogun lo lọ ṣe ipade na. Ninu igbimọ yi, Amẹrika damọran wipe ki igbimọ yan awọn enia lati lọ ba awọn igbimọ ilẹ Egypt wipe ki nwọn jẹ ki ebute Suez jẹ ọna ti ọkọ gbogbo aiye yio mario laisi wahala tabi iyọnu, nwọn si fi ọrọ yi si idibo, awọn ilu mẹtadilogun lo gba wipe ki a ran enia lọ silu Egypt.

Prime Minister ilu Australia ni yio ṣe aṣiwaju awọn enia na lọ sibẹ awọn ti yio lọ ni Amerika, Sweden, Persia, ati Ethiopia.

India sọ wipe on ti on rope o dara ni, ki nwọn jẹki Egypt gba ilẹ ini wọn pada, Suez, ṣugbọn ki awọn igbimọ rẹ jẹ ti gbogbo agbaiye.

Ṣugbọn Nasser ti o nṣe Premier fun ilẹ Egypt nsọ̣ ọ, o si tun ntun sọ wipe awọn ko ni gba ki ilu ajeji kan ma wa paṣẹ ninu ilẹ Baba wọn, lori ohun ini wọn. Bi ebute na ba wa lọwọ Egypt awọn yio ma ṣe itọju rẹ, gbogbo ọkọ ilukulu ni yio si ni anfani lati gba ebute na kọja.

Ọgbẹni kan ninu awọn Gẹsi sọ wipe, nkan ti awọn Egypt nfi oju ọkọ Gẹsi ati ti Faranse ri ni ebute yi ko sunwọn lati gbọ.

## Elewon kan lu Ajele

GBOKO. Ọkunrin kan ti a npe ni Sabo Abudulahi nilu Gboko lo daran ofin ti nwọn si ju si ẹwọn oṣu mejidilogun.

Ajẹlẹ dide lọ si ọgba ẹwọn nipa ọrọ ti Sabo Abudulahi yi, nitoripe, o sọ pe ẹjọ ti nwọn ju on si ẹwọn fun yi ko tẹ on lọrun.

Ṣugbọn nigbati Sabo fi oju kan Ajẹlẹ yi, ninu ọgba ẹwọn, o sare mọ̣, o kan lẹṣẹ. Lori ẹṣẹ ti o kan Ajẹlẹ yi ni nwọn tun ba a ṣe ẹjọ Adajọ ni ki nwọn lọ na a ni ẹgba mejila nidi rẹ. bọni oju rẹ da wayi.


## Kere o!

A ti ni oriṣiriṣi ogun Germany to ṣẹṣẹ de, fun oniruru aisan tọkunrin tobinrin. Tete wa ra tirẹ k'o to tan.

**J. A. AJAO BROTHERS**

MEDICINE STORES

7, Egerton Road, Lagos


## Tani Le Se Kio Gba Ebun

(O bẹrẹ loju kẹrin)

ni Oloye na nigbati o lọ si mẹka ati Mẹdina.

14. Lọjọ wo, oṣu wo, ati ọdun wo ni Oloye Eletu odibo de fila fun Ọba Falolu, Gomina wo lo si mbẹ nigbana?
15. Ọdun wo ni ijọ C.M.S de si Eko. kini orukọ alufa ti o mu ijọ na de si Eko?
16. Ọdun wo ni ijọ Aguda de si Eko kini orukọ Padi to mu wa? Nibo ni ẹni to mu ẹsin na wa ti wa?
17. Ọdun wo ni nwọn ṣi ọja Ita Faji tani ẹniti o kọkọ sọrọ nibi ṣiṣi ọja na?
18. Tani ẹniti o kọko kọle pẹtẹsi nilu Eko, nibo ni pẹtẹsi na si wa?,
19. Ọdun wo ni ọkọ ofurufu kọkọ fo de ilu Eko?
20. Ọdun wo ni Dokita Ọlọrunnimbẹ di Mayor nilu Eko ọjọ wo lo si fi oye na silẹ?

Ao ma reti esi o.

## GRAMMAR LEDE YORUBA

Idaraya miran tun de fun gbogbo awọn ti o ba gbọ ede Yoruba. Ẹniti o ba ṣe tirẹ ko fi ranṣẹ si Lemọmu Ajakuta c/o 28 Kọsọkọ St, Lagos.

1. Fi ede Oyinbo tunmọ awọn ede Yoruba nwọnyi:- Agogo-Tumọ rẹ si ọna mẹta.
2. Ọmọ - Tumọ rẹ si iye ọna ti o ba mọ si,
3. Iya - Tumọ rẹ si iye ọna ti o ba mọ.
4. Ilu - Tumọ rẹ si ọna marun.


**Fun Agbara ise l'osan**
**Fun alafia lehin ise ati ere sise**

Hommel's Haematogen fun enia l'agbara gẹgẹbi akọ Malu, tabi bi irin ati awọn nkan miran ti o nmu ara le. Pẹlu agbara Ọkunrin, gbogbo awọn ọmọ rẹ ni yio ni Agbara.




**HOMMEL'S HÆMATOGEN**

O MBẸ NINU IGO FUN TITA KAKIRI ṢỌBU GBOGBO ILẸ NIGERIA

ati lọdọ Aṣoju wa :-

**ALBAN PHARMACY LTD.**

2, Victoria Street, LAGOS    P. O. Box 461, NIGERIA,

## Talo Ye Ki O Fe Obinrin Na ?

OLOTU.

Jọwọ gba mi laye lati ṣe ibere yi lọwọ awọn ọjọgbọn ọkawe rẹ, ki nwọn o fun mi ni ọgbọn ati oye nipa rẹ. Awọn ibere mi na niwọnyi:—

Baba kan wa o bi ọmọ-'kunrin meje, orukọ ekini ama jẹ Mọrin-mọrin, ekeji M'ọna-m'ọna, ẹkẹta Mọ-'lu-mọ'lu, ẹkẹrin, M'enia-m'enia, ẹkarun, Mọ'yan-mọ'yan, ẹkẹfa, Jukumọ-jukumọ, ati ekeje, Mọhan-mọhan.

Ni ọjọ kan, baba wọn pe awọn ọmọ na jọ, o sọ fun wọn wipe ki nwọn lọ wa nkan wa ni orişirişi fun on.

Awọn mejeje bọ s'ode, Mọrin-mọrin, l'o siwaju wọn, nigbati wọn rin, rin rin, ti wọn de opin ọna, wọn pe M'ọna-m'ọna, wọn ni iṣẹ kan ẹ o, M'ọna-m'ọna, bọ si waju laifa ọrọ gun, wọn ja oju ọna, wọn nlọ titi, wọn ko kan ilu, nigbati ara fẹ mu wọn, wọn pe Mọ-'lu-mọ'lu wọn ni iṣe kan ẹ.

Mọ'lu-mọ'lu bọ siwaju wọn, laipẹ wọn kan ilu kan, nigbati nwọn wọ ilu na, wọn ko mọ enia kan nibẹ. Wọn ni iṣẹ kan M'enia-m'enia, on na bọ siwaju bẹ ni wọn pade olowo kan ni M'enia-m'-enia ba ki, o ni ki wọn kalọ sile, nigbati nwọn ba de ile rẹ, oṣe wọn l'alejo jijẹ ati mimu ni o fi tẹ wọn l'ọrun.

Wọn wa pe mọyan-mọyan, wọn ni iṣẹ kan ẹ, o bọsi ita, o bẹrẹ si yan, o nyan kakiri ilu, ibẹ ni obinrin kan ti ri, o ni enia lo mọyan bayi, on yio fẹ ọkunrin yi, o sunmọ, o ki i, o sọ fun wipe on yio fẹ ẹ. Obinrin na jẹ iyawo Olu-Ọdẹ ọkọ rẹ jẹ Ọgbogi Oniṣegun ilu na, Mọyan-mọyan si da lohun wipe alejo ni on, ayafi bi o ba le ba on salọ, obinrin na ni o ti ya.

Gbogbo wọn dide, nwọn npada lọ si ilu wọn ati obinrin na. Ọmọ kan wa lọ ṣe ofofo fun Olu-Ọdẹ wipe awọn alejo kan ti gbe iyawo rẹ salọ. Olu-Ọdẹ si ni ogun pupọ, o ran ẹiyẹ aṣa kan o ni ki o lọ gbe iyawo on wa, Aṣa fo o ba wọn lọna, o nra baba lori wọn, kia o gbe iyawo on ngbelọ s'oke, nwọn ni iṣẹ kan Jukumọ-jukumọ.

Jukumọ-jukumọ ni koiti rin s'oke to, igbati o lọ si oke rere, ni o ba ju kumọ kan s'oke, kumọ ba aṣa ni apa, Aṣa ju obinrin silẹ, bi o ti mbọ nilẹ, nwọn ni iṣẹ kan Mọhan-mọhan, lọgan ni Mọhan-mọhan ba han obinrin na, kojẹ ki o ba'lẹ rara.

Ẹjọwọ, ẹnyin ọkawe wa aladun yi, tani o yẹ ki o fẹ obinrin na ninu awọn mejeje ?

Emi ni
Y. Ade Buraimoh

---

## E Ma Ka Iwe-Irohin Eleti-Ofe Ki Esi Ma Polowo Oja Yin Sinu Re.

---

# OBA PELU AWON MINISTERS



Aworan oke yi nlti Alaiyeluwa Ọba Obinrin ilu nla London pẹlu awọn ọlọla Alakoso Ijọba (Prime Ministers) orişirişi ilu to mbẹ ninu Ajumọṣepọ ti gbogbo agbaiye (Commonwealth). Alaiyeluwa fun awọn ọlọla na ni arakuyamu adidun onjẹ alẹ ninu Alafin ọba.

Awọn Alakoso Ijọba na niwọnyi lati ọwọ-osi — Ọgbẹni Strydom (South Africa) Ọgbẹni Mohamad Ali (Pakistan) Ọgbẹni Holland (New Zealand) Ọgbẹni St. Laurent (Canada) Oloye nla Sir Anthony Eden (Britain) Alaiyeluwa ọba ilu Gẹsi, Ọgbẹni Menzies (Australia) Ọgbẹni Nehru (India) Ọgbẹni Bandaranaike (Ceylon) ati Lord Malvern (Federation of Rhodesia and Nyasaland). Eyi ni ipade keje ti nwọn ṣe lẹhin ogun ajakaiye.

# First Western Regional Government Lottery

## Ere Orire Akose nilu Ibadan

Eyi ni sho ere Orire ti Ijoba Iwo-Orun koko se nilu Ibadan ni ojo kedogbon osu August, 1956.

O le ni egbeji enia ti o peju pese woran nigbati awon ota orire na ni Gbongan ola Mapo, ti gbogbo enia si gba wipe ko si eru ninu re.

Irufe Orire bayi dara pupo nitorine o ma ngbe ilu ga ni, yio so talaka di olowo, nipa be, ilu yio si ma ni ilosiwaju rere. Ope ni fun Ijoba Iwo-orun

Awon ti o s'orire je owo girimoyan ni a to si isale yi nonyi:- Ogbeni Ayudubie Ogbewe A 34 Urekuosa Village care Post Office Box 245 Benin City lo je 1st prize £ 5000.

Zaccheus Oyederu Attorney General Chamber Western Region Ibadan lo je 2nd Prize £2000.

Peter A. Awale Itsekiri N. A. New Hdqrs Warri, loje 3rd prize £1000.

Awon enia mewa je ogerun poun fun enikokan.

Awon ogun enia je adota poun fun enikokan.

## Iyafin Segilola S'ehin Iya Re

Ni ojo Tuesday ose yi ni Iyafin S. [illegible] O. Shogbola se iranti odun kejiidilogun ti iya re ti fi aiye sile, eko re Ogbeni S. Ola. Shegbola Olori ile oja Shegbola Stores, ati oluta Keke Aiup pu ti a npe ni Auto Rex Cycle nile wa nihin se awewo to gbadun fun awon ojulumo ati ore ni komadan ile re, ni 87, Agege Motor Road, Idi-Oro.

Ogbeni D. B. Williams ti ile ise P. W. D. Ijoba l'o se alaga, Ogbeni J. O. Hyde soro iwuri nipa iya na, ogbeni Shogbola si fesi to jire si oro re.

Igbadun ojo na ko f'enu so, bi Ero gbohun-gbohun ti nkorin beni ilu juju ndun bi arira. Ogbeni E. B. Adeniregun, akowe owo ti Nigerian Union of Transport lo se olutoju eto ojo na si itelorun gbogbo awon alabaseye ojo na.

Ki Oluwa fi orun ke iya na o.

## Iwadi Oro Nipa Rogbodiyan To Sele Ni Ilorin

ILORIN, Eniti ijoba yan lati se iwadi oro nipa rogbodiyan ti o se ni Ilorin laipe ni Ogbeni Bax.

Eniti o koko bo siwaju wa rojo ni Malam Lamulu Ayinla, ti o ngbe Abule Adekanbi l'eko Ilorin; on lo rojo bayi wipe, nipa rogbodiyan ti o be sile ni Odo Sadu l'ose to koja, oju on l'ose.

Awon enia mejidilogun ninu awon ara Abule on ru isu lo si oja l'ojo buruku osu gbomimu na fun tita; on si ri die ninu awon enia ti o ntele Daudu oba lehin, ti nwon nso fun awon enia wipe ki enia wipe ki enikan mase ba won ra isu, nitori ara omo egbe Talaka Parapo ni nwon nse.

Awon iranse nwonyi si ko awon agbe ti o wa ta isu na, nwon ko merindilogun ninu nwon lo sodo Daudu, Daudu si fi won le olopa lowo. Nwon ba won s'ejo ni Kotu Ilorin, nwon ni ki awon enia na lo san Poun mejilelogbon.

Eniti o tun soro ni Tafa Laniyan, okan ninu awon ti nwon dano sun ile re lasiko rogbodiyan na. O so wipe on ko mo eniti o dana sun ile gan, sugbon o ni lati je awon apa keji ni igba pupo ni awon iranse Daudu ti ma ndena de on loju ona. Eniti o tun soro ni, Malam Imoru, o so wipe lojo kan awon iranse Daudu wa ba on nile pe, Alkali npe on ni Ilorin. Nigbati on si tele won ti nwon de odo Daudu, nwon lu on pupo, die loku on fere daku. Bi ejo na ba ti nlo si, ao ma gbo.

## Ipade osu ketaketa

Ipade "Ajo Babalawo" ti osu kaketa ni ao se l'agbara Odu'a ni ilu "Gbongan "ni arin "Oja" (ki ise ni ile Araba) Gbongan ni ao ti joko se ipade na ni ojo kejo osu Owewe 8th Sept, 1956. Ao bere ipade na ni agogo mewa gan (10. a m).

Gbadebo Dosumu,
akowe ijo Babalawo.

123

# PUBLIC NOTICE

Applications are invited for the post of Assistant Lecturer at Yaba Technical Institute. Particulars in Government Notice No. 1576 in the Federation of Nigeria Official Gazette of the 23rd August, 1956.

Applications should be directed to the Secretary, Federal Public Service Commission, Private Bag No. 2586, Lagos.

Closing date 8th September, 1956.




M.B.T.
(MAGIC BLOOD TONIC)
Ina de, okunkun parada. M.B.T. de, okunrun fo lo. Eje dudu sare, oyi posese. Ala buburu wo'gbo, ailesun r'ehin-ekun. M.B.T. logun-eje ti nmu ni jeun b'ikan, amu ni yagbe bi okun, amu ni to bi akere. Abiwere ; aboyun, agbejedi fawon abiyamo. Ahon-dudu, ese-wiwu ati aiya-jija ko si fenití nlo o.
4/6d pelu 1/6d owo-oko.
ARADAN STORES P.O.Box 2, EBUTE-METTA.

KEKE BASIKULU TO LAGBARA JU





Ranti wipe awon irin ise KEKE PHILLIPS, gegebi awon ohun ti afi nda KeKe duro, ibiti a ngbe ese le ati bawonni, je eyiti olokiki kakiri aiya, wipe tiwa lo lagbara julo ti osi dara. —KeKe Basikulu ti Phillips ti afi irin ise Phillips se je eyiti Kolegbe Ni Gbogbo Agbaiye.

Malo Basikulu Ti PHILLIPS

KEKE BASIKULU TI AFI IRIN TUTU SE

PHILLIPS CYCLES LIMITED · BIRMINGHAM · ENGLAND


Printed & Published by The Union Printing and Publishing Company, 28 Kosoko Street P. O. Box 467 Lagos Phone [illegible]